# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KẸFÀ, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**Àdúrà Lòdì Sí Àjẹ́ Olórogún**

**Oṣù Kẹfà – Àdúrà Lòdì Sí Àjẹ́ Olórogún**

# <u>ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀</u>

1. **Ọlọ́run 'bùkún a yìn Ọ́**

A nkéde or'ọ̀fẹ́ Rẹ
'Wọ olúgbalà Wọ mímọ́
Ògo f'órúkọ nlá Rẹ

Ògo, ni fún ọ́kọ Rẹ,
Ológo ni orúkọ Rẹ
Ògo, ni fún Ọ́kọ Rẹ
Ológo ni ókọ Rẹ,

2. Olùràpadà Olúwa

Ìmọ́lẹ̀ àti àìlópin
Káwọ́n mímọ́ gbogbo kọrin
Òdodo àt'iyìn Rẹ

Ògo, ni fún ọ́kọ Rẹ,
Ológo ni orúkọ Rẹ
Ògo, ni fún Ọ́kọ Rẹ
Ológo ni ókọ Rẹ,

3. Láti ìtẹ́ ògo t'ọ̀run

Dé orí àgbélèbú
Ìwọ kú ikú 'ràpadà
Láti gba ẹlẹ́ṣẹ̀ là.
Ògo, ni fún ọ́kọ Rẹ,
Ológo ni orúkọ Rẹ

Ògo, ni fún Ọ́kọ Rẹ
Ológo ni ókọ Rẹ,

4. Wá Ìwọ Olúwa Ìyè
Wá gúnwà ní ìtẹ́ Rẹ
Wá láti jọba tító lái
Kí ijọ̀ba jẹ́ Tìrẹ.

Ògo, ni fún ọ́kọ Rẹ,
Ológo ni orúkọ Rẹ
Ògo, ni fún Ọ́kọ Rẹ
Ológo ni ókọ Rẹ,

1. Nípà ìfẹ́ Olúgbàlà
Kì yó sí nkan
Ojúrere Rẹ kì padà
Kì yó sí nkan
Ọ̀wọ́n l'ẹ̀jẹ̀ tówò wá sàn
Pípé lèdìdí or'ọ̀fẹ́
Agbára l'ọwọ́ t'ógba ni
Kòlè sí nkan

2. Bí a wà nínú ìpọ́njú
Kì yó sí nkan
Ìgbàlà kíkún ní tàwa
Kì yó sí nkan
Ìgbẹ́kẹ́lè nínú Krístì l'érè

Ẹmí sìn so wá di mímọ́
Kòlè sí nkan

3. Ọjọ́ ọ̀la yó dára
Kì yó sí nkan
Gbàgbọ́ lè kọrin nínú pọnjú
Kì yó sí nkan
Agbẹ́kẹ̀lé ‘fẹ̀ Bàbá wa
Jésù fún wa l’óhun gbogbo
Ní yíyè tàbí ní kíkú
Kò lè sí nkan.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n fi iṣẹ́ rán láti jí ẹ̀rí mi lónì, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
2. Agbárakágbára òkùnkùn, tí wọ́n yàn láti dámidúró kí n má á lè dé ibi ìmúṣẹ ayànmọ́ mi, ìjì iná yóò pa ọ́ run lónì, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo májẹ̀mú ìpàdàṣẹ́yìn nínú iran mi, nípa agbára tó n bẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ rẹ lónì, ní orúkọ Jésù.
4. Ilé agbára òkùnkùn, tí wọ́n yàn láti daàmú ìtẹ̀síwájú ayànmọ́ mi, àrá iná láti ọ̀run yóò tú ọ ká lónì, ní orúkọ Jésù.
5. Ìbápàdé àtòkèwá, tí yóò ru títàn mi sókè, ayé mi wà fún ọ, farahàn nínú ayé mi lónì, ní orúkọ Jésù.
6. Ìwọ agbára Ọlọ́run tí ó pín Òkun Pupa níyà, bẹ ayé mi wò pẹ̀lú ìfọwọ́kàn àwọn ìyanu, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, Ìwọ ní O dá ọ̀run àti ayé, jẹ́wọ́ orúkọ Rẹ tí n ṣe Jah nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo májẹ̀mú ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n jìyà lárin ọ̀pọ̀ yanturu, fọ́, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára tí wọ́n yàn láti jàmílólè àwọn ànfàní ìláágùn mi, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, nípa ọwọ́ iná àti àrá Rẹ, tú gbogbo ẹ̀mí tó n mú ìlọ́ra bá itẹ̀síwájú mi ká, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá mi, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe ṣẹlẹ̀ sí Gòlíátì, túká, kí O sì parun gbogbo ẹ̀mí ìbíntín àti ìdárungún, ní orúkọ Jésù.
7. Mo fagilé gbogbo ìfẹ́ àti àsọtẹ́lẹ̀ òdì nípa ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Ìsáíàh 40:29:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; Ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá.

**Fílíppì 4:19:** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ Rẹ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Orin Dáfídì 107:20:** Ó rán ọ̀rọ̀ Rẹ, Ó sì mú wọn lára dá, Ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.

**Orin Dáfídì 147:3:** Ó mú àwọn onírora àyà lára dá: Ó dí ọgbẹ́ wọn.

**Ìsáíàh 57:18-19:** Mo ti rí ọ̀nà rẹ, èmi ó sì mú u lí ara dá: èmi ó sì tọ́ ọ pẹ̀lú, èmi ó sì mú ìtùnú padà fún u wá, àti fún àwọn aṣọ̀fọ̀ rẹ̀. Èmi li ó

dá èso ètè; Àláfíà, àláfíà fún ẹnití ó jìnà réré, àti fún ẹnití ó wà nítòsí, ní Olúwa wí; èmi ó sì mú u lí ara dá.

**Rómù 8:37:** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí àwá ju ẹnití ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ́ wa.

**Máttéù 9:21:** Nítorí ó wí nínú ara rẹ̀ pé, Bí mo bá ṣá lè fi ọwọ́ kan aṣọ rẹ̀, ara mi ó dà.

**Deuterónómì 7:15:** OLÚWA yóò sì gba àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ, kì yóò sì fi ọ̀kan nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀, sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn ó fi wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Ìsáíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Jeremíàh 17:14:** Wò mí sàn, Olúwa, èmi ó sì sàn; Gbà mí là, èmi ó sì là; nítorí ìwọ ní ìyìn mi.

## <u>ÀDÚRÀ LÒDÌ SÍ ÀJẸ́ OLÓROGÚN</u>

1. Gbogbo odò òṣì tó n ṣàn nínú ìran mi, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo odò àìláṣeyọrí tó n ṣàn nínú ìran mi, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
3. Igi ìpọ́njú nínú ilé bàbá mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ọfà ìpọ́njú, tí àjẹ́ olórogún ta sínú ayé mi, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.

5. Àyídáyidà àjẹ́ olórogún lórí àṣeyọrí mi, kú, ní orúkọ Jésù.
6. Agbára ẹ̀rọ ìdarí ibi ilé bàbá mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára búburú tí wọ́n gbìn sí ìpìlẹ̀ ayé mi, láti máa tọpinpin ìtẹ̀sìwájú mi, gba ifàtu nípa iná, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo agbára òkùnkùn ilé bàbá mi, tó n ṣagbátẹrù àwọn iṣòro igbàdégbà nínú ayé mi, àkókò rẹ ti dópin, kú, ní orúkọ Jésù.
9. Mo sọ̀rọ̀ ìparun sí gbogbo iṣẹ́ àjẹ́ olórogún nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo iṣẹ́ àṣeparí àjẹ́ olórogún nínú ìdílé mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Ẹrù búburú ilé bàbá mi, tó n mú ìlọra bá ìtẹ̀sìwájú mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ìfẹ́ búburú àwọn àjẹ́ olórogún fún ayé mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ìdibàjẹ́ tí àjẹ́ olórogún ṣe sórí ayé àti ayànmọ́ mi, gba ìfagilé nípa agbára tó n bẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.
14. Àgádágodo àjẹ́ olórogún, tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.